

Aworan yi ni ti iwuye Oba Alaiyeluwa Adenuga Kini, ti o je Oba Olowu, Ijebu-Owu ni aipe yi. Awon ebi, ore ati gbogbo awon alabaseye ni o rogba yi ka yi nigbati o njade bo lati inu ile Olo un "Saint Michael Church", Ijebu-Owu lehin isin idupe. Lehinna ni awon Owu National Society wa seye fun un ninu Gbongan Apejo Ilu. Ki ade pe lori ki Bata pe lese o.

# IWE SI OLOTU IROHIN YORUBA

## *Agbako Ejo N'Ilu Komu*

OLOTU, Mo kí nyin pupọ, ẹ ku iṣẹ ribiribi ti ẹ nṣe, Oluwa ki O fi ibukun si i. Inu mi yio dun pupọ bi ẹ ba le gba mi laye ninu iwe nyin lati sọ ọrọ diẹ lori ọrọ ti awọn Ọgbẹni M. O. Babayẹmi ati A. O. Akinrinde sọ sinu iwe nyin ti 10/ 5/ 54. O daju pe ire ilu wọn ni nwọn nfẹ, ẹniti o ba si fẹ ire fun ilu wọn ire Oluwa, a ma a ni inu didun si iru ẹni bẹ ẹ.

Bi ẹ ti bere fun iranlọwọ, a ti ba nyin gba adura, a si bere lọdọ Oluwa, Oluwa si wipe "Awọn ejo yẹn ti ẹ sọ pe o npa awọn enia ki iṣe ejo ni bikoṣe awọn enia. Ẹ wo Iwe Dafidi Ori 5 ẹsẹ 9.

Nigbana ni mo si bere lọdọ Oluwa pe, ọra wo ni alafia yio fi wọ ilu na? Oluwa si fi esi pe, bi awọn Ọgbẹni meji na ba le ni igbagbọ si ọmọ Ọlọrun Jesu Kristi ti nwọn ba si ranṣẹ si mi pe awọn gba a gbọ de aye ti nwọn yio fi gbagbọ pe Oluwa yio gba wọn, ki emi ba wọn lọ si ilu na, ati pe bi emi ba de ibẹ Oluwa yio ṣe Olutọ mi lori ohun ti emi yio ṣe.

O si ni ki emi ṣe iran" ti pe a ti kọ iwe rẹ pe, "Lorukọ mi ni nwọn yio le ẹmi eṣu jade, nwọn yio ma a gbe ejo lọwọ, bi nwọn ba si mu ohunkohun ti o li oro lọwọ ki yio pa wọn lara. Wo Marku ori 16 ẹsẹ 18. Oluwa papa si ti sọ pe imọlẹ ati okunkun on ni on da wọn. Isaiah ori 45 ẹsẹ 7. O ni ẹ kọju si on, on o si gba nyin la ẹsẹ 22.

Bi ẹnyin arakunrin meji na, Ọgbẹni M. O Babayẹmi ati Ọgbẹni A. O. Akinrinde ba fi imọ nyin ṣe ọkan ti ẹ si ranṣẹ lati bere iranlọwọ Ọlọrun, Oluwa yio si ṣe e.

Awa nreti esi iwe yi lọdọ ẹnyin arakunrin mejeji, ki ẹ si ṣe apejuwe fun wa li ẹkun ọna ti a le gba de ilu nyin na.

Awa ni ti nyin ninu ifẹ Jesu,

Evangelist V. I. Olu Popoola ati Z. Adesanya,
29, Forestry Road,
BENIN CITY.

E MA A POLOWO OJA NYIN SINU IWE Irohin Yoruba

## *E Ba Ni M'oju To Oran Eko*

INU mi yio dun pupọti ẹ ba le gba mi laye lati sọ ẹdun ọkan mi fun gbogbo aiye gbọ ninu Iwe Irohin Yoruba ti o nfi ọna han awọn ope yi nipa ti ọrọ "Ile wiwo" ni igboro ilu Eko si etigbọ awọn Alaṣẹ Ijọba ilẹ wa.

Họwu! kini kuku ṣe? "Imado ibaṣẹ bi ẹlẹdẹ a ba ilu jẹ, ẹru iba jọba enia ko ku kan" nitori awọn ile diẹ ni arin ilu Eko ko dara, ki a si ti ọkọ ati diga bọ gbogbo ilu, ki a ma a wo gbogbo ile lọ? họwu! ki l'okuku ṣe?

Ẹ jẹ ki a rin gbogbo ilu wo, awọn ile ti o ba buru ju ki a wo wọn kuro, ẹ ma jẹ ki Ijọba tiwa jẹ ti Ọba Oseruru d'ẹgan o, bikoṣe Ijọba o s'ẹgan d'erufu. Olotu, mo dupẹ o, Olodumare ko ni gba ilu wa na lọwọ wa o. Aṣẹ.

Emi ni,
S. B. OLUBI
3, Braimoh Street,
Od.-Olowo,
Mushin.

## LAKAYE ORO

Ẹ maye dani li ẹjọ, ki a ma ba da nyin li ẹjọ.
Nitori iru idajọ ti ẹnyin ba se on ni a o si se fun nyin, iru oṣuwọn ti ẹnyin ba fi wọn, on li a o si fi wọn fun nyin.

Matteu 7: 1 - 2.

# AKIYESI ATI ATUNSE

Nipa Jakọbu ori 21 ẹsẹ 17-26 ti Ọgbẹni Aiyerujana Parrot ti Baptist Church, Gudi bere pe on ri ka ninu idahun T. A. Odusọla si ibere Ọlọrunlogbọn ninu Iwe ti 17/5/54 ni oju ewe kẹta ṣugbọn on ko ri Jakọbu 21 ninu Bibeli, otitọ ni, Jakọbu ori 2 ẹsẹ 17-26 ni, ki iṣe ori 21. A dupẹ lọwọ ẹniti o tọkasi aṣṣe kekere na. Ẹ ku iṣẹ o.

OLOTU


# IRORA ORISIRISI

IRORA OJIJI TABI EYI TI O NG MU ARA GAN

Nigbati awọn eree "Kidneys" ba nṣe iṣẹ ti nwọn si nfẹ eebon iwo yio ... mọ lara ọe awọn ewu mbọ. Didun ... ... ṣe ikan ninu ewu na. Eyi fi han pe awọn eree re ko ... wọn taara. Iṣẹ na ... ki nwọn maa ṣe awọn idọti kuro ninu ara.

A ṣe "De Witt's Pills" lati ṣe iranlọwọ gan ni fun awọn eree re ki nwọn ba le maa ṣiṣẹ ... Nipa awọn ohun ti nwọn fi ṣe, egbogi na yio ki nataki ... ti o nṣe ki ara maa dun ni wọ. Egbogi na yio ti awọn idọti ti o nṣe ki ara maa dun ni jade, ko de ni si irora mọ.

... nipe awọn ọpọlọpọ ... awọn enia ti nwọn ti ni irora orisirisi ti ... lẹhin igbati nwọn ti lo egbogi yi ti nwọn ... pe iṣẹ rẹ dara.

Kini ṣe ti iwọ na ko fi ni tete ... fun aisan tire? ... 



De Witt's Pills jẹ egbogi pataki fun ẹhin didun, Iwora, Lakuregbe, Arinka, Tanlatan ati bẹẹ bẹẹ lọ.

IJERI SI WA

Egbogi De Witt's Pills jẹ eyiti a ṣe pẹlu imọtoto ti gbogbo awọn eroja ti a fi ṣe ... jẹ pipe.



DE WITT'S PILLS
for Kidney and Bladder Troubles

